# ỌBA ADELE DAGBERE FUN GOMINA AGBA


**Ikede**

Aw Ikede yi f o a gbogbo ... Okuwe wa ati asoju wa wipe, Ẹni kẹni ti owo ba sẹku ti owo re ki o tete fi ranṣẹ nitori gbogbo ohun elo ti a fi ntẹwe irohin lo ti gbe owo leri. Sakun ti ko ba fi tire ranṣẹ ... da iwe rẹ duro ao si sa agbara lati gba owo wa n owo re. Olotu



# ELETI ỌFẸ

A-NJU-WỌN KO ṢE WI ...EJỌ



**Just Arrived**

Sta dard Cookers the newest Scientific invention without wick, pump and injector, no el ctricity required.

Call at Sylvo & Company

4 Oshodi Street Lagos.

At Corona Cookers, Stoves, and buy to avoid regrets.



Vol. VII No. 409 LAGOS (SATURDAY) ỌJỌ ABAMẸTA APRIL 2 1955. IYE OWO ELETI ỌFẸ KOBỌ MEJI.


## Iga Idunganran Miringindin Qba Adele Dagbere Fun Gomina Agba



**Eko** Irohin ko to afojuba lojo Monday nigba ti Alaiyeluwa Oba Adele fi se awuyewuye ti idagbere fun Gomina Agba Sir John Macpherson ninu iga Idunganran, eniti ko le rin ni ki a gbe on

Awon egbegbe ti o wa sibe ni egbe Savage, egbe Ojikutu, egbe Ereko, egbo Faji, Ebute-Ero, Aromi, Ebute-Elefun, ati Idera. Awon omoba, awon Hausa, Ilorin.

Die ninu awon alejo ti o wa ni Alaiyeluwa Oba Ijebu Igbo Oba Oko, Oba Gbagura, Asoju awon Ologboni Abeokuta ati awon ijoye Eko.

A soju Oyinbo Japan, India, Syria, Amerika, DaRocha Jibowu, Sekiteri agba ti Eko awon oyinbo ti o nse Panla Faranse, Doctor Manuwa ati awon enia pataki miran ti a kole daruko re tan.

Awon Ijoye Eko lo pade Gomina papaa ni enu Qwa on pelu iyawo re bo sile ninu moto, nwon si fi ese rin wo Iga. Awon Qlopa sise ribiribi lojo na, Oba Adele lo ka oro iwuri n'pa Gomina, Gomina papaa soro t ti o wipe on ko ni gbagbe ara ile yi

## Ọgbeni Oduleye Jona Raurọu Ninu Idibo Munisiba

**Eko** Iyafin Elsie Femi Pearse, ti o nse iyawo Dokta Pearse, ọkan ninu Ẹgbẹ Afẹnifẹre li o bori ninu ibo ti a di ni Yaba lati fi yan enia si ipo ti Ọgbẹni Kola Balogun fi silẹ.

Enia meji li o du aye ipo na Iyafin Peare (Afẹnifẹre) ati J. A. Oduleye ti ko ṣe ẹku ko ṣe ẹiyẹ Iye enia ti o dibo fun Iyafin Pearse je 351, ti Oduleye je 60 Pearse fi ọgọ'a tayọ eyi jeki Oduleye padanu owo iduro.

Ọgbeni Animaṣaun ati I. S. Martins ni awọn ọmọ ẹgbẹ Afẹnifẹre meji ti a tun yan si igbimọ ti ko si eniti o le ba wọn du ibo na.

Nwọn yan Animaṣaun dipo Ọgbẹni Ogunbiyi nwọn si yan Martins dipo Nduka Eze.

## Irohin Iwo Orun Ile Nigeria

Okan ninu awon oro ti a fe lati ma so losose lori ero Asoro-magbesi (Nigerian Broadcasting Service) n'pa isesi ati ilosi Ijoba Iwo Orun, yio si bere li ojo Ajemisi, ojo kokanla osu April 1955 li ago to meji ... .

Asale onirohin Ijoba Iwo Orun (Western Nigeria Information Service) ni yio ma mu awon irohin oro ti ao so na wa. Irohin ti nwon yio mu wa na ni, ao pe lori ero Asoro-magbesi bayi wipe ("Western Nigeria Magazine").

Awon Qlotu ilu wa (Ministers) yio ma wa soro nigba gbogbo nipa gegebi ise won ti lo si. G... bi ise Ijoba ti nlo si ni ao so pelu Orin, Ere ati ... Ao tun ma so awon oro pataki miran, eyiti a ... bayi wipe, 'Nje iwo mo ?" Ao se irohin pata ... awon Qdomokunrin ati Qdomobinrin, eyiti a ... fun awon Odo" Ao si la won loye gegebi ijo ... ti nse ise won si, Ni ewo jije ati ni idaraya ... won.

Aye wa fun enikeni lati kowe bere oro, bi o ba si to akoko lati dahun awon ibere na ao fesi fun Oluwa re Bi a ba si ba oro de ibi "Mo mo awon eni nwon yi, awon oro ti ao so nibe ni oro nipa igbesi aiye awon enia ti o nse olotu Ijoba Iwo orun (ile Yoruba)

Nigbati ao ba koko bere eto yi, Qlola Anthony Enahoro ti o je wipe labe re ni gbogbo ase irohin wa, yio se alaye gegebi eto titun yi ti wulo to. Sir John Rankine, Qloi... Gomina yio soro. Lehin na ni Oloye Qbafemi Awolowo yio tun soro pelu

Fetisile lagogo mejo ... li alale ni gbogbo ojo Monday lati gbo irohin yi, bi o ba ti gbo oro yi wipe Western Nigeria Magazine.


**Kere o! Kere o!! Kere o!!!**

Gbogbo Rekodu ti O. B. olorin aladun ni.

Eniti o ba nfe rekodu fun gramafonu tab fun ampl'faya to gbadun, awon bi OB. 4 ni ag d gbo, OB. 7 OB. 8, OB. 9, OB. 10 OB. 11, OB. 12 OB. 13, OB. 14, OB. 15 OB 16, OB. 17, OB 18 OB. 19, OB 20, OB. 21, OB. 22, OB. 23, OB 24, OB. 25 at ot ... ti ko si aye lati daruko wa fun tita n sọbu Ọgbẹni Oshunkọya:-

OSHUNKEYE SOUND SERVICE RECORDS
161, Victoria Street, Lagos.

tabi kakiri gbogbo sọbu ti nwọn ti nta rẹkọdu. Sa bere O. B. Rẹkọdu. Tete sure wa ra tirẹ tabi ki o kọwe ọwọ. Irohin ko to amojuba o, ore mi.




Ol... la Sir John Macpherson Gomina agba ti ... le Nigeria eniti yi fi ile o s lo ni ojo 12. 4. 55. Odigba o

## Awon Qlopa Fe Dagbere Fun Go...

Eko Aw... bere ... bi nwon ns ... Gomina Agb... odigboṣe.

Er... ijo ... a ye ... go maru k j ... n jin ... Ij Alaruba 6th osu Apr... 1955, Nw... o gb... a a j ba Gen la ... wa f ko Qlọl Gomina ninu wu oye re.

Gbogbo eniti o ba nfe ri ... ya w... n ki o kowe lọgba t k ti ijo ... o i d Assistant Staff Officer gerla Police Tinubu Sq. Lagos.

# ELETI QFE

A NIUSWỌN KO SE WI L'EJO

...ICE & WORKS    CABLES & TELEGRAMS
... Lagos    "ETI-QFE LAGOS"
Box 467    Phone 23370

... 48. LAGOS SATURDAY APRIL 2 1955.


## Ijoba Enia Dudu

Gbogbo enyin okawe wa ti e ti nri irohin ka li okan ko jo okan ninu iwe irohin wa yi, ati ninu iwe irohin miran ni yio ti gbo nipa gbogbo ipade ti awon asoju wa se ninu igbimo nla (House of Respresentative) ti nwon nse lowo-lowo yi nilu Eko.

Li ola si tabi-tabi, gbogbo nyin ni yio ti fi eti gbo nipa ise awon olukuku awon enia ti a yan kakiri igun mererin ile wa sinu igbimo na. Ohun ti awa Eleti Qfe akiyesi ni wipe ninu gbogbo ipade ti nwon ti nse, ... igbimo ote yi je.

Ekinni ni wipe, awon Gesi fi aye sile fun awa enia dudu diedie, lati wo, bi ao tise ijoba ara wa si, nigbati nwon ba gbe ijoba na le wa lowo.

Ekeji ni wipe, eto yi fun awa enia dudu laye lati ni enu ninu oro ilu wa, obe ti o fi je wipe, ohun ti a ba so pe ... ijoba Gesi yio ba wa fe, on si ni abage.

Eketa ni wipe, Aseko ti ao gba ominira nile wa kusata sugbon ... ni ao ti se ijoba na? Qpo enia ni okan won ... lo i ghelehun oro yi. Oninu ... aiya si nlo wa Qpo enia rope ijoba ti oyinbo dara ju ti enia dudu lo.

Sugbon bi eyin okawe wa ba deju sile, ti e si wo bi gbogbo nkan ti nlo si, e o ri daju wipe aimokan-aimokan lo nmu ekute ile pe ologbo ni ija, alaimokan li o nyo won lenu lati rope enia dudu ko le da ijoba ara won se.

Iselu ti awon oyinbo ko tayo eyiti awa enia dudu papa nse lo, enu ibiti nwon baa de ni a ti bere yi, ohun pataki ti o ku nisisiyi ni wipe, ki a se atilehin fun ara wa. Ki Olorun si ran wa lowo.

Bi awon Osela wa ba ti nri awon atilehin mejeji nwon yi, ko si ewu, beni ifoya ko si lori wipe bawo ni ijoba enia dudu yio ti ri.


## Ikede

THE NIGERIAN OFFICE STATIONERY SUPPLY STORE

... wipe, awon ti si sobo ohun kan ati ile ise titun ... awon gbe nkan Rubber Stamp.

... ni ... Street, legbe ile ise moto ti oyinbo F... (C. F. A. O. Motor Garage) lojo Alamisi 31st March 1955 ni agogo ... owuro ni ao si ile yi.

A ti ... arowoto eyin onibara ni ilu Ibadan nisisiyi.

THE NIGERIAN OFFICE STATIONERY SUPPLY STORE
18/22 Willoughby Street
P. O. BOX 145, LAGOS
LAGOS, NIGERIA.


## E Ka Iwe Irohin Eleti Qfe


## EHIN DIDUN PẸLU IRORA



Qna wo ni ẹyin lo fi ko irora?
Nje iwo mọ pe ọkan ninu ohun ti o nfa ... ẹhin didun ni Kidinrin?
Bi ohunkohun ko ba se Kidinrin wa nwọn a sọ gbogbo eri kuro ninu ẹjẹ ki gbogbo ẹya ara wa le ma ṣiṣẹ dede nigbati Kidinrin wa ba nse ... o, ti ko si ... dede, gbogbo eri a wọjọ sinu ẹjẹ a si ma a mu ki ẹhin dun ni.
Egbogi onirodorodo fun gbigbemi ti Ogbẹni De Witt se je egbogi atata a ti ... atamatase ti o nmu ki ẹhin dun ni salọ kakiri nipa titun ẹjẹ se ati nipa nimu irora ati alafia ba eniyan ti ẹhin didun nn yoba je.
O san ki ẹnitì ẹhin didun nba ja sete fi egbogi ti a nsoro rẹ yi ko loju fun ati ba le je igbadun aiye jupe ki a fi dagunla ki o si madi eni bẹ be lọwọ lẹnu iṣe rẹ ati ni igbesi aiye rẹ.
Egbogi De Witt je egbogi ti a ti nlo lati aiyebaye wa, titi o fi di oni yi ko ... wiwo ẹhin didun san ti ẹgbagbeje enia ti o ti lo De Witt lo nkan sara si fun jijẹ bi idan rẹ. Nitori idi eyi, ogunlogo iwe ni nwọn kọ ẹwọ siwa lati fi dupẹ fun ere ribiribi ti De Witt nṣe fun wọn. Lo si le tita egbogi ki o lọ ra tirẹ loni fun fifo nitori ijafara lewu.



A ṣe DE WITT'S PILLS nipataki fun wiwo.
ẸHIN DIDUN
IRORA ORIKERIKE
LATANLATAN
IBADI SISANNI
A lọwọ ṣeya pe De Witt jẹ ojulowo egbogi. Gbogbo ohun elo ti a si fi ṣe e lo pe peropero ti awọn alaṣẹ ilera ni kan sara si pe ko si koṣoṣe kankan nipa rẹ

# DE WITT'S PILLS
for Kidney and Bladder Troubles



# Enjoy Your Own Songs

SUNG BY YOUR OWN PEOPLE IN THE WAY YOU LOVE MASTERLY RENDERING OF TRADITIONAL AFRICAN MUSIC IS YOURS ...



OBTAINABLE FROM:
## The Association Of Nigeria Gramophone Delears
THROUGHOUT NIGERIA



## Plushes, Velvets, Velveteen, Damasks, & Building Materials

PLEASE CONSULT :

# Okunowo Brothers

63, Massey Street, (Faji Market)
LAGOS, NIGERIA.
The House where Courtesy & Satisfaction are Guaranted.

## Awon Babalawo So Wipe Ipori Awo Ọkanre Nise

**Gbogan** Nini ipade igbimọ ti awujọ awọn Babalawo lọ ṣe nilu Gbogan li ọjọ 8th ọṣn March 1955 ni ita Oinfa, eniti o ṣe alaga rẹ ṣo pa ni Awofisan ti o nṣe aṣoju Araba-nlo Olu Ifẹ.

Ọrọ ti awọn ṣe ipinnu le lori ninu igbimọ na ni wipe (a) Ọjọ kanna ni ki gbogbo awọn Babalawo ma ṣe ọdun Ifa tabi Ọdun Ọrunmila, jake jado ilẹ Nigeria (b) Gbogbo edekoyede ti o mbẹ lara Awo si Awo ti bi lati a Ọmọ Awo si Awo, ki awọn nṣe pe wọn ... si pari rẹ. (d) ki awọn Araba ati Oluwo ni ... ra wọn pelu Ọba ilu wọn. (e) Ki gbogbo awọn Oluwo ati Araba ni ipade ... awọn le ni ... nje ... ti ijọ ti oju agba ... Babalawo ... gbo, ipọ

## Oyinbo Onisowo John Holt Sile Titun

**Eko** Awọn Oyinbo onisowo ti a npe ni John Holt. kọ ile titun kan si opopo Broad Street araga nile, a si gbọ wipe iye owo ti awọn fi kọ ile na, ẹrẹbọ ni.

Irohin ko to afojuba niki ṣile yi, nitoripe ọpọlọpọ ni gbajumọ ati awọn oyinbo ti o wa nibi ṣile yi.

Diẹ ninu awọn ti o wa nibẹ ni Ọgbẹni M. T Mbu, R. A. Njoku, L. P. Ojuku, Alhaji Kenku, A. A, Kosington, Alia Odunuga, J. K Ogunnsike.

Diẹ ninu awọn Awo ti o wa ni Fatokun Abere Ifa, F.A. Ajanaku aṣoju Araba Eko, Ṣonbarẹ Akọwe Awofisan aṣoju ara Ifẹ, Alebiọsu, Ogunyebọ, ... Arohunfẹsu, Ọṣuntade, Amusan Jogbodo Ọrunmilo, Ipayẹ, Akofa, Orisa-Ṣọna, Fadara, Ojugbọna.


"Yes, I prefer

SHELL X-100 Motor Oil–

*it's proved itself in my car"*



EVERY time your car starts, every time it stops, corrosive acids form inside the engine. They are active *even when the car is not in use.* By eating into vital engine parts and slowly destroying finely machined surfaces, these acids do more damage than friction can ever do. Corrosive acid attack leads to blocked oilways, loss of power, unnecessary and harmful dirt, excessive wear, and many other troubles. You cannot prevent acid formation. You *can* protect your engine from its effects by using Shell X-100 motor oil, always.

This oil has been developed by Shell scientists to neutralise engine acids and so provide positive resistance to corrosive acid attack, 24 hours out of 24. Cars that run on Shell X-100 motor oil benefit from:

- Cleaner engine
- Reduced engine wear
- Smooth full power performance
- 24-hour protection from corrosion
- Longer engine life

... ay, too. Always ... lubricant, best

SHELL X-100 MOTOR OIL


## Epo Moto Seyo Ni Ilu Jos

**Jos** Ọkunrin kan ti a npe ni Sedu Kabilo li Ọlọrun ṣe okan fun, ni akan ti o le fa awo gọbọyi wa fun.

A gbọ wipe, bi ọkunrin yi ti nggẹ kanga ninu ọgba rẹ fun omi beni o lo kan orisun epo moto ti a npe ni Gas Oil.

Ọkunrin na sare lọ so fun Ọba Jos, Ijọba ibilẹ ti bu dile lara epo yi, nwọn si ti fi ranṣẹ si ijọba Gẹsi ni Kaduna lati yẹ epo na wo bi o ba jẹ eyiti o dara.

Nwọn si ti awọn ọlọpa ibilẹ sidi Kanga na lati ma ṣọ ki ẹnikan maṣe de ibẹ.

## Iye Enia Ti O Mbe Ninu Ise Olopa

**Eko** Oriṣiriṣi eya enia ti o mbẹ ninu iṣẹ Ọlọpa Iye awọn Ibo ti o mbe ninu iṣẹ na jẹ ẹgbẹji din logberin le logojẹ (325) Awọn Yoruba jẹ ẹgbedinlẹgbẹta le mẹkandinlaa-goji (1361) Ibini ẹdẹgbẹrin din meji lelogun (688) Kalaba ati Obioble jẹ irinwo le mẹrin-lelogoji (434 Kamaru jẹ ọdunrin le mẹrin lelaadọta (354) awọn Ijẹ jẹ ọdunrin le meji (302 awọn Hausa ọdunrin le kan (301) Isobo jẹ igba lemarun-dinlọgọta (255) Awọn Fulani je mẹkaudilogọrun(99)

## Egbe Afenifere Lo Bori Ni Ilu Ilesa

**Ilesha** Ninu awọn Ibo ti a di ni egbegbe ilu yi laipẹ yi, awọn ọmọ ẹgbẹ Afẹnifẹre li o mbori lọna-kọna.

Ni ilu Kiriji, ẹgbẹ Afẹnifẹre lo ko gbogbo ayo mẹjidilogun ti o ṣi silẹ nibẹ, awọn ijoye mẹrin ti o tun wọle pelu, jẹ ẹgbẹ Afẹnifẹre.

Awọn ẹgbe yi na li o lori ni Ibokun ati li Ẹsa Oke.

## Ika Ko Sunwon

Awọn ẹgbe Maṣe Ika si eranko (R.S.P.C.A.) ti de Ilẹṣa. Awọn ẹgbe awọnyi nkọ enia wipe Ika si eranko ko sunwọn, nitori bi a ba fi pepe gun ọmọ eiye t a si tun fi gun ọmọ enia wo, bi o ti ndun ọmọ enia beli o ndun eranko. Ẹni kẹni ti o ba ṣe ika si eranko, tabi ti o lu, tabi ti o lo si ilokulo nwọn o ba oluwa rẹ ṣe ejọ, akọwe ẹgbe na ni Ọgbẹni Ọladimeji Oṣoegbure.


NOW,
AVAILABLE

BUGLES, BEDSTEADS
PAINTS DISTEMPERS,
SAFES Etc,
Just write, Call, or
Phone 21372
IKORODU TRADING
COMPANY
20/28, Balogun Street,
(P. O. Box 395) Lagos.
AND
NEW COURT ROAD
IBADAN

## Iwe S Ijoba Ilorin

Olotu,
Jowo gbami laye lati sa si ijoba ibile Illorin k awon se lowo awon odoo ti a nfe awonyi fun wa.
Nigbati a reti wipe ki Ijoba ibile Ilorin le oju ona moto fun wa, ti e ko si koye won, Nigbana a o roo Ijoba wa wipe owo ara eni li a fi nlan iwa eni se. A d de fanra wa si la oju ona moto na lati ilu Ojojulade si Offa. Ina wa yio dun bi Ijoba ibile Illorin bale lowo oun fo oko fun wa
Olorun jeki emi oba Ilorin gun fun wa ati awon ijoye re. Ohun ti a tun nfe ni ho iwosan ati wipe nisisiyi Post Office yio kari aiya ki ijoba maso gbogbo lati gauti eruke Olotu fun won si awon le ke okan fun wa. Oro na ko ju eyi lo

Emi ni,
Alufa Lawani Ba-reke-Ladi
Ara Oke Oya

## Ibere Lodo Awon Qmo Qba

Olotu,
Jowo gba mi laye lati se ibere gbolohun oro yi lodo awon omo oba ilu Yoruba ki awon fi ye wa

1. Eniketi ti o ba ti gun ori oye oba, gbogbo ati ra ... oba na, Omoba ni ao ma pe ... yala iran oba na tun pada joba tabi ko joba mo.
Sugbon bi eniken ba gun ori oye oba na si wa buwa t o jod si ile gbogbo ara ilu re tobe ti awon ni lati yo kuro lori oye oba na. Lehin ti a ti yo oba yi kuro lori oye ti o wa bi omo k a n. Nje a ha tun le ka omo ti o bi na kun awon omoba ilu na tabi ko le je Omoba,
2. Omo kan i e'a bi sori oye ti ko mo iwe, ati eyiti oba bi lehin ti a ti yo kuro lori oye ti o si le omowe tabi leya ti awon moj'ji odu oye oba mo ara won lowo. Tali o ye ki o joba na?

Emi ni,
Alufa Imam Adeen

## Bawo Li Qro Yi Tiri

OLOTU,
Jowo gba mi laye lati bere awon oro nwonyi lodo awon ok we re.
1 Eso ti awon fi npe awon Onilu ni Alagbe?
2 Kini idi r. ti awon Onilu ko nei fila niwaju Oba?
3 Kilofa ti awon Onilu ko fi ako owo ti nwon ri gba dele ti nwon so pin?

Emi ni
W. S. Odebiyi

## ... gbe ... ko Mba Aiye Je

Olotu,
J... se Olotu, oje bi a ba npe enia ni ole o ba ye ki Olowa ro ma gba omo eran (leran lo bi? Mo gakiyesi wipe die ni awon enia ti o fe ao ilu re nlan egbe N.C.N.C. ko tile deni loju wipe awon enia na nronu rara.
Bi o ba se wipe Iro inakuna, ti nna yi ni won ti nna ni Kolani Nibo ni ijoba iba ti ri owo ti nwon fi ra ilu Porthecourt ni odun 1917 nwon si wa Iraalowo lo si ibi ti iran'owo ko si, abuku na ni niwonyi:-
Nwon o! ki gbogbo awon Gomina meje san owo ori mo Nwon fi kan owo Osu Azikiwe Nwon taku lati fun awon osise ni Sile meje abo.
Pelu-pelu lati gba ti nwon ti gun o ite ijoba akoiti ri o ohun anfani kan ti nwon se Agbalagba ti obin elo ika omo re yio je nibe

Emi ni
Lemomu Ajakula

## Ki Lemomu Lo Simedo

Olotu,
Aki tori Awijare ki Ilo ku tan ni enu Jowo gba mi laye lati dahun si oro Lemomu Ajakula ti o so pe iro ni awon enia npa mo Jesu Oro ti Jesu so ki awon enia nso Tani enia o p ro mo Jesu Oruko re ti oje ati iru oro wo ni oni na so ti ki se oro ti Jesu so? Matteu Luke, Marke ati Johanu ti o soro nipa Jesu nwon jo ohun ti won ti oje a'i eti gbo
Tani ki a gbagbo. Eniti oro sofu re ni tabi eniti ko a nibe? Olorun ko fi owo ara re ko iwe kankan bikosepe o se oro re fun enia awon ni ko sile gege bi Mose ti ko oro ti Olorun so sile.
Bi ajaye ba tun le wa oro ojuro yi ko ye mi.

Emi ni
Animashahun,
Ara Abidjan

## Qro Iyanju Si Ara Iragbiji

Olotu,
Jowo gba mi laye lati so oro iyanju die yi si awon ara Iragbiji Jesu nigba aiye re li o so bayi wipe, e fi ohun ti o se ti ijoye fun ijoye, Bayi ni a le tumo oro Jesu nasi.
E jeki a se gbafara fun ohun ohun kohun ti o je ohun abuku ki a si yo egan ara eni kuro li okan, emo tani eyiyi, tabi oleyi ewo!
Bi o ba ri ilu kan ti o po ti ohun gbogbo si te won lorun, ko si ohun meji ti o gbe won de ibe lehin Ife ati Ododo. Nitoripe Ododo li o ngba orile ede leke.
pelupelu bi awa ko ba ni Ife ki ni awa ba nse si oju iwa Odale? Iru iwayi ko le mu ilosiwaju wa silu wa, nitoripe egbejo owo owo, li a fi nso aiya, Oju ko fera ku.

Emi ni
B. A. Ajagbe,


## Imoran Fun Eyin Abiyamo

Eyin abiyamo ewo se 'Omorela' O dara pupo fun awon omode

A ma je ki omode ri oran sun daradara, o dara fun ehin, Iko ati ... aras ... ti o ma aba omode je ni aisike ohin, Opolopo abiyamo lo ti lo egbogi yi fun omo won ti won si so wipe o dara pupo fun awon omode.

**Omorela Baby Mixture**

SILE MEJI ABO (2/6d) FUN IGO KAN ... re lodo

**Commercial Medicine Stores**

QUALIFIED CHEMIST
10, Victoria Street LAGOS.



**REDIFFUSION**

THE BOX THAT TALKS SINGS & BRINGS MUSIC TO YOUR HOME

Costs less than 3d a day and gives you pleasure for 17 hours.

MAINTAINANCE FREE!
ARE YOU A SUBSCRIBER?


## ILEWE QFE ALAKQBERE TI IJQBA IWQ ORUN

## (ILE YORUBA)

IFORUKO SILE Bere kakiri lati ojo 24th osu March titi di ojo 7th osu April 1955.

A nfe awon omode were ti o dagba to odun mefa, sugbon ti koiti to odun meje, ninu osu January 1956.

AWQN QMQ TI O TI BERE SI JE ANFANI EKQ QLQFE TI ALAKQBERE NISISIYI FERE TO ADQTA QKE (1,000,000)

Lo fi oruko awon omo re sile ninu ilewe Alakobere ti a ti da sile, larin agogo meta osan si agogo mefa irole ni gbogbo ojo, ayafi ojo Sunday, larin ojo 24th March si 7th April 1955 ki nwon ba le gba omo re si ilewe ninu osu January 1956.

## Ogbeni Enahoro Lo Be Ilesha Wo

**Ilesha** Li ojo Thursday k a n, ninu osu March 1955 ni Ogbeni Tony Enahoro da kan lo be ilu Ilesha wo, lati se abiyesi eto awon Olopa ibile.

O ba awon igbimo Osise ti o wa labe ijoba ibile Ilesha se ipade nwon si soro pataki larin won Councilor Ayo-ola to koko iwe ti awon Osise fi ki Ologa Enahoro.

Asho wipe okan ninu awon oro pataki ti o gn fi enu kan ni oro nipa ...ni nwon o fi je aye Ripoto (Inspector) fun awon Olopa ijoba ibile Ilesha. A ale Olopa papo alle wa.


## SINMETI TI OYINBO BURHAM NI A FI KO



### ILE EJO ILU ACCRA

Awon ile ejo ti a sese ko nwonyi mbe li arin ilu awon Aganyin ni Accra, o si je apere ilosiwaju ti a se fun idagba soke ile enia dudu. Simenti Oyinbo Burhama ti Portland se iranlowo gidigidi ninu kiko ile na ati awon ile ola-ola miran lakiri ile enia dudu. Simenti Oyinbo Burham ti nse iralowo yi fun iwon ad orin oduh sehin. O si ti fi nan gbamgba wipe Simenti ti Oyinbo Burham li o lagbara julo ti o si diraju, on ni a s ie gbeke.e ni gbagbo agbaiye.

**BURHAM**

PORTLAND CEMENT

BURHAM BRICK LIME AND CEMENT CO. — BURHAM — PORTLAND CEMENT — WORKS — LONDON


OWO TI ONISEGUN NA

**Eko** Sabi wa Bata Odi ... Onisegun ti o fun won ni agbogi jedi-jedi ti o di ... ti gba owo rasa si ni owo Olopa. ti ... sisiyi, o mbe ni kotu Olopa.

## O Ye Ki Ijoba Wadi Awon Osise Fanand po

**Fenandopo** Ogbeni Jala Wasak ... o here wipe, ... o ... ko je ... ngbo ... Fenandopo nipa ... awon osise ile ... awon Oyinbo Peyan ... ki oloto awon Osise (Minister of Labour) se wadi wo, ... alafia awon enia na ... ati iru ... wo ni awon enia ... wa nilu Fenandopo ti ni Gabon.

Obun ti a gbo wipe awon Peyan nse fun awon osise ati awon alejo ti o wa se owo nibe na ni wipe, awon Payan lo nse oko Gesi fun ... nwon lo ... gba ki ... owo ile ... jade.

Bi ... ki ... ni ilu ... [illegible] ... Fenandopo.

Feleyelu ... ni awon ... nje awon Osise, o si dabi ... nwon ... lo oko o'u.


## SECOND H ND CL THING

| | |
|---|---|
| Women's long Coats | 2/- |
| Women's Short Coats | 1/- |
| Women's Dresses & Frocks | 1/- |
| Women's Skirts | 1/- |
| Costumes | 3/- |
| Men's Raincoats | 5/- |
| Men'sJackets | 1/-6d |
| Men's Waistcoats | 6d |
| Men's Felt Hats | 1/-6d |
| Men's Khaki Greatcoats | 20/- |
| Men's Ex-Service Overcoats | 10/- |
| Men's Overcoats-Civilian | 5/- |
| R. A. F. New Side Caps | 1/- |
| Men's Suits | 20/- |
| Ex-Army Blankets | 7/-6d |

Noless than 250 supplied.
We have also Radiograms £10: 0s: 0d
Secondhand Pianos £10: 0s: 0d
Organs £10: 0s: 0d

Prices quoted ex-warehouse. C.I.F. charges extra. Immediate attention. Writefor full price list. Enquiries invited.

H. NEWAMN & Co (MERCHANTS) LTD.

[illegible]

Manchester, [illegible]

Cables: "Recovery" [illegible]



[illegible]

A ti ... o ... Germany to sese de fun onirure aisan to' unrin to'rin-rin. Tete wa ra tire ... fun

J. A. AJAO BROTHERS

Medicine Store

7, Egerton Road, Lagos

## Ijoba Si mi Ero Si Ilesha



**Ilesha** Lasiko kan ti awon ara Osogbo ati Ilesa so wipe awon afe omi ero, Ijoba ko wipe awon lo mu egberun ... ijoba yio fi ero kan na fe omi si Ilesa ati Osogbo ti ko je ogun buru lo ara won.

Ijoba Ibile Osogbo lo koko fi owo lele, lehin na ni Ede, ki Ilesa to wa fi ere tele. Awon ojogbon so wipe Odo Osun o ma gbe ... nigba ... kojeko awon ti pa Osogbo ati Ilesa po.

## Dokita Olumide Jare

**Eko** Ejo ti Ijoba ure pelu Dr. Oluyinka Olumide, okan ninu awon Onisegun ile Alaisan Iddan ... o jare ejo re ni waju Adajo A.R. Dickson.

Awon gbajumo enia lokunrin ati lobinrin ti o wa gbo gegebi awon ti ma de ejo yi ... le ni irinwo

Adajo so wipe Olumide ko jebi niwonpe awon Olopa ko se iwadi oro won daradara

Nigbati adajo ... o siwaju ro ... sehin o so wipe Dokita Oluyinka ... Olumide ko jebi esun na, nitori na ki o ma lo li alafia.

---

Nipa iranlowo Ogbeni E. A. Babalola ni Ijoba lo ero anfani kan fun Ede ati Osogbo lati ina Ode Eyinle, ti ko nghe laseko yen.

Lehin ti awon pari afami ti Ede ati Oshogbo, ni awon bere Afami ti Ilesha. Nwon si si ero afami ti Ilesha ni apari osu March ti odun yi

Ogbeni Babalola ti o ... asoju ile fun ise (Minister of Public Work) ti o lo si ... ero na.

---

## Aradan Nervigora




Ogun ti ... fun ... agba ati ... pipe ... O dara ... ati arun ... ise ... 5/-6d ...

**The Egba Trading Ardan Stores**

144, Denton Street, 19, Denton Bridge Street, P. O. Box, 2, Ebute Metta. Phone 44135

a tun wa ni New Motor Park (Ogunpa Ibadan.

---

## Ikede Ijoba

O KU OJO MARUN PERE LONI TI A KO

NI GBA ORUKO SILE MO

WA FI ORUKO OMO RE SILE FUN EKO.

... TI ALAKOBERE FUN ODUN 1956

... ti o ba je alakobere ni a ngba

... O TI O TI DAGBA TO ODUN MEFA.

... KO TI PE ODUN MEJE GERE, LI A

NF... GBA NI BERE ODUN 1956 TI O MBO

... ere to adota oke awon omo ... ti nje ... o Olofe yi, eyiti Ijoba Iwo Oorun ... omode keke e ti o mbe labe ... ijoba ile won.

---

## WESTERN REGIONAL PRODUCTION DEVELOPMENT BOARD

### INDUSTRIAL MANAGER

The Board invites application for the post of Industrial Manager who will be responsible for advising on Industrial Policy investigating industrial projects and supervising the operation of industrial schemes in which the Board is interested.

Candidates should possess a University degree or comparable professional qualification and have had considerable management and industrial experience. Normal age limit 30 to 40 years. Salary to be paid will depend upon the qualifications and experience of the successfull candidate and be in the range of £2,500 to £3,000 per annum.

Application giving full details of qualifications and experience should be addressed to :-

The Secretary,
Western Region Production Development Board,
Secretariat,
Ibadan.

(giving the names referces) to reach him not later than 30th April, 1955.

---

## DEPARTMENT OF INFORMATION SERVICE

### WESTERN REGION

### VACANCY FOR POST OF EDITOR

Applications are invited from suitably qualified Nigerians for appointment to the post of Editor in the Department of Information Services, Regional Headquarters, Ibadan.

SALARY SCALE:- The salary of the post will be in the Scale A. 3. The point of entry will be £850 per annum plus 10o/o contract addition and £100 per annum gratuity.

QUALIFICATIONS:- Candidate should have had at least 5 years experience in journalism in a newspaper of wide circulation, including at least two years editorial responsibility. A knowledge of documentary or news-reel film commentary production would be an additional qualification.

DUTIES:- The officer will be required to take charge of the production of a weekly Government newspaper in the Western Region; to supervise the editorial production of the daily and weekly publication of proceedings of the Wester.. Regional Legislature; and to supervise the production of commentary for Government sponsored news and documentary films.

OTHER CONDITION OF SERVICE:-

(1) The appointment will be made on a three years' contract.

(2) It is unlikely that Government quarters will be available.

METHOD OF APPLICATION, etc.

Applications shoud be addressed to the Secretary Public Service Commission, Western Region, Ibadan, so as to reach him not later than the 11th April, 1955

Applications from candidates not in Goverment Service should be completed in duplicate on the prescribed form which may be obtained from all Residents in charge of provinces, and from the Nigeria Information Service in Lagos, Ibadan, Kaduna, Enugu and from the Public Service Commission Ibadan. Application from candidates in Goverment Service should be submitted through the Head of the applicant's department and be accompanied by a Confidential Report on the new Confidential Report Form.

Printed & Published by The Union printing and Publishing Company, 29 Kosoko Street P. O. Box 467 Lagos, Phone 23370